# YIYAN IYAWO

## Gẹnẹsisi 24:1-33

## ẸKỌ 12 --- FUN AWỌN ỌDỌ

**AKỌSORI: "On mọ̀ ọ̀na ti emi ntọ̀" (Jobu 23:10).**

**Abrahamu ati Isaaki**

Nitori igbọran Abrahamu, Ọlọrun ti ṣeleri fun un pe lati inu ẹbi rẹ̀ ni a o ti bukun fun gbogbo orilẹ-ede aye. Abrahamu ti di ẹni ogoje ọdun nisisiyii; aya rẹ̀, Sara, ti kú; ọmọ wọn, Isaaki ti to ẹni nnkan bi ogoji ọdun. Ọlọrun ti bukun Abrahamu, O si ti fun un ni ọ̀wọ́ ẹran, ati agbo ẹran pupọ, fadaka, wura, awọn iranṣẹ-kunrin, awọn iranṣẹ-binrin, rakunmi ati kẹtẹkẹtẹ pupọ. Isaaki jẹ ajogun gbogbo nnkan wọnyii. Abrahamu ni iranṣẹ oloootọ kan ninu ile rẹ̀, iranṣẹ ti o dagba ju lọ ti o si n ṣe akoso lori gbogbo awọn nnkan ti o ni, ẹni ti a gbagbọ pe oun ni Elieseri ara Damasku.

**Iṣẹ Pataki**

Ni ọjọ kan, Abrahamu pe iranṣẹ oloootọ yii ti a ti danwo, o si sọ fun un lati ṣe iṣẹ pataki kan. "Lọ si ilẹ mi, ati si ọdọ awọn ará mi, ki iwọ ki o si fẹ́ aya fun Isaaki, ọmọ mi." Awọn obi ni wọn maa n saba yan awọn alabagbe fun awọn ọmọ wọn, gẹgẹ bi a ti maa n ṣe ni orilẹ-ede miiran titi di oni paapaa.

Ni tootọ eyi jẹ iṣẹ ti o le fun iranṣẹ yii. Boya ọdọmọbinrin ko ni fẹ́ já gbogbo ide ile ati awọn ọ̀rẹ́ lati rin irin-ajo ti o jin to bẹẹ. Ṣugbọn oluwa rẹ mu ki o da a loju pe "OLUWA Ọlọrun ọrun … yio rán angẹli rẹ̀ ṣaju rẹ." Abrahamu bẹ̀rù pe bi ọmọ oun ba fẹ ọmọbinrin lati inu ẹbi awọn ara Kenaani, a le tan an lọ kuro ninu isin Ọlọrun tootọ.

**Pipinya pẹlu Ayé**

Awọn ti wọn n tẹle Jesu, ti wọn si ti fi ayé silẹ lẹyin, jẹ ọ̀kan pẹlu Ọlọrun ati Kristi. Ọlọrun ti rán Ẹmi Mimọ Rẹ̀ sinu ayé lati lọ si ọdọ awọn "ará" Rẹ̀, ki o si mù Iyawo fun Ọmọ Rẹ̀, Jesu Kristi. Awọn ti yoo ṣe Iyawo Kristi ni awọn ti a ti gbala kuro ninu ẹ̀ṣẹ wọn, ti a si ti sọ di mimọ́ patapata, ti wọn ti tẹ siwaju ti wọn si ti ri ifi-agbara-Ẹmi Mimọ wọ ni gbà. Diẹ kinun ni ibaṣepọ ti awọn eniyan ayé ni pẹlu awọn ọmọ Ọlọrun tootọ. Wọn kò ni inu-didun si ohun kan naa; wọn ki i lọ si ibi kan naa; wọn ki i fẹ bá ara wọn kẹgbẹ pọ̀. Ka 2 Kọrinti 6:14-18, ki o si kọ́ pupọ si i nipa ipinya awọn Onigbagbọ́ pẹlu ẹgbẹ buburu ati awọn alaigbagbọ.

**Irin-Ajo naa Bẹrẹ**

Lai si idaduro siwaju si i, Elieseri mura fun irin-ajo rẹ̀ gba aarin iyanrin aṣalẹ kọja lọ. Awọn rakunmi mẹwaa ti a di ẹrù pupọ le lori ni ẹgbẹ ero yii; ọrẹ olowo iyebiye wà ninu ẹrù yii. Nigba ti gbogbo nnkan wà ni imurasilẹ, Elieseri ati awọn eniyan rẹ̀ dide wọn si lọ.

**Ni Ibi Kanga Omi**

Ni ikẹyin, irin-ajo ti o to nnkan bi ẹẹdẹgbẹta mile pari. Ni oju alẹ, awọn rakunmi mẹwaa yii ti aarẹ ti mú, ti oungbẹ si ti gbẹ wọ́n, kunlẹ ni eti kanga ni ẹ̀yin ode ilu Nahori, ni ilẹ Mesopotamia. Bi o tilẹ jẹ pe alẹ n lẹ́ lọ, sibẹ iranṣẹ oloootọ yii pinnu lati pari iṣẹ rẹ̀ ki ilẹ ki o to ṣú. Kanga jẹ ibi ti eniyan ti le pade awọn ọdọmọbinrin ti wọn n pọn omi ni irọlẹ.

**Ẹmi Mimọ́**

Bawo ni eyi ṣe jẹ apẹẹrẹ to ni ọjọ oni -- Ọlọrun Baba, ti Abrahamu duro fun nihin, ti rán Ẹmi Mimọ́ lati wá Iyawo fun Ọmọ Rẹ̀ Jesu Kristi. Nisisiyii, nigba ti ọjọ alẹ ogbologbo ayé yii n lẹ́ lọ, Ẹmi Mimọ́ n wá Iyawo ki ilẹ to ṣú. Lai pẹ Ẹmi yoo dẹkun lati pè, Iyawo yoo si wọle lọ si Ase-Alẹ Igbeyawo ti Ọdọ-Agutan (Wo Ẹkọ 342, Fun awọn ọdọ, Iwe 27).

**Adura ati Idahun**

Njẹ a ko le ri Elieseri bi o ti tẹ ori rẹ ba ti o si gbadura soke kikan: "OLUWA, Ọlọrun Abrahamu oluwa mi, … kiyesi i, emi duro li ẹba kanga omi yi; … ki o si jẹ ki o ṣe pe, ọmọdan ti emi o wi fun pe, Emi bẹ̀ ọ, sọ ladugbo rẹ kalẹ, ki emi ki o mu: ti on o si wipe, Mu, emi o si fi fun awọn ibakasiẹ rẹ mu pẹlu: on na ni ki o jẹ

ẹniti iwọ yàn fun Isaaki iranṣẹ rẹ; nipa eyi li emi o si mọ̀ pe, iwọ ti ṣe ore fun oluwa mi.” O n fẹ ami kan ki o ba le mọ̀ pe Ọlọrun n tọ́ oun ninu wiwá iyawo fun ọmọ oluwa oun.

Ki adura yii to pari, ọdọmọbinrin arẹwà kan wá si ibi kanga pẹlu ladugbo ni ejika rẹ̀. A sọ pe ni Mesopotamia, ejika ni a maa n gbé ladugbo si, nigba ti o ṣe pe ni orilẹ-ede miiran, ori ni a fi maa n rù u. O sọkalẹ si ibi kanga, o si pọn omi kun inu ladugbo rẹ. Iranṣẹ naa sare lati pade rẹ, o si beere omi mimu lati inu ladugbo rẹ̀ wá. Pipa oungbẹ rẹ ko saa ṣe pataki fun un nisisiyii bi i mimọ̀ boya ọmọbinrin yii jẹ idahun si adura rẹ̀ tabi bẹẹ kọ. O gbe ladugbo rẹ̀ sọkalẹ sori ọwọ rẹ̀ kánkán, o si fi tọ̀wọ̀tọ̀wọ̀ fun un ni omi mu. Iranṣẹ naa ko beere omi fun awọn ibakasiẹ ṣugbọn ọmọbinrin yii fi tinutinu yọọda lati pọn omi fun awọn ibakasiẹ pẹlu. O n lọ, o si n bọ̀, o si n fi ladugbo rẹ̀ pọn omi fun awọn ibakasiẹ mẹwẹẹwa ti oungbẹ ti gbẹ, titi wọn fi mu omi tán. Ibakasiẹ ni àyè ninu ikun rẹ̀ lati gba omi ti yoo to lo fun ọjọ mẹwaa si mẹẹdogun.

**“Ẹni-ibukún OLUWA”**

Ẹnu ya iranṣẹ yii pupọ, inu rẹ̀ si dùn, o mú oruka wura ti eti ati jufu wura meji fun ọwọ rẹ̀, o si wi pe, “Ọmọbinrin tani iwọ iṣe? Emi bẹ̀ ọ, wi fun mi: àye wà ni ile baba rẹ fun wa lati wọ̀ si?” O yara dahun pe àyè wa fun un ati fun awọn eniyan rẹ̀ ati fun awọn ibakasiẹ pẹlu. Nigba naa ni o sare lọ si ile lati sọ fun ẹbi rẹ̀ itan ajeji ṣugbọn ti o jẹ iyanu, nipa ohun gbogbo ti o ti ṣẹlẹ. Arakunrin rẹ̀, Labani, lọ si ibi kanga lẹsẹ kan naa, o si sọ fun Elieseri pe oun ti pese àyè silẹ fun un, ati fun awọn ibakasiẹ pẹlu … O si wi pe, “Wọle, iwọ ẹni-ibukún OLUWA.”

**Ayè ninu Ọkàn**

Ẹmi n wá ọ kiri lati mura ọkàn rẹ silẹ fun ipadabọ Oluwa ti ko ni pẹ mọ. O fẹ ki o wà ni imurasilẹ lati jẹ ọ̀kan ninu Iyawo Kristi. Njẹ o n kọ ipè naa bi? tabi o le wi pe, “Wọle; ẽṣe ti iwọ fi duro lode? Mo ti pese àyè silẹ ninu ọkàn mi fun Ọ.”

## AWỌN IBEERE

1 Ki ni ṣe ti Abrahamu fẹ ki Isaaki fẹ́ ọkan ninu awọn ibatan rẹ̀?

2 Ta ni ni aṣẹ lori gbogbo ohun ini Abrahamu? Ẹni ti a le gbẹkẹle ni bi?

3 Bawo ni iranṣẹ yii ṣe rin irin-ajo la aṣalẹ já?

4 Iru adura wo ni iranṣẹ yii gbà?

5 Bawo ni o ṣe mọ̀ pe a dahun adura oun?

6 Sọ iwa Rebeka.

7 Apẹẹrẹ ta ni Elieseri i ṣe? Ni ọna wo?

8 Sọ diẹ ninu awọn ohun amuyẹ ti Iyawo Kristi.

9 Njẹ a fi tayọtayọ gba iranṣẹ yii si ile Rebeka? Ki ni a ṣe fun un?